Office for National Statistics

UNIVERSITY OF OXFORD

Department of Health & Social Care

**Olùbásọ̀rọ̀ ìwádìí** (England): **0800 085 6807**
**Olùbásọ̀rọ̀ ìwádìí** (Wales): **0800 917 9323**
**Olùbásọ̀rọ̀ ìwádìí** (Northern Ireland): **0800 917 5825**
**Olùbásọ̀rọ̀ ìwádìí** (Scotland): **0800 917 5824**

# Ìwádìí lóòrí àjàkálẹ̀-àrùn COVID-19

Kópa nínú ìwádìí ńlá kááàkiri àgbáyé lórí àjàkálẹ̀-àrùn COVID-19. **Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ rẹ yóò ràn wá lọ́wọ́ láti mọ ìhà tí o yẹ kí a kọ sí àjàkálẹ̀-àrùn yí, kí a padà sí ìgbésí ayé ìrọ̀rùn.**

AYẸWO

## Kíni ìwádìí yìí dálé lórí?

- Èrèdí ìwádìí yìí ni láti mọ iye àwọn ènìyàn ti o ti lùgbàdì àrùn COVID-19, yálà àrùn náà ti fojú hàn tàbí kò tîì fojú hàn.
- Ìwádìí yìí tún jẹ́ ọ̀nà láti ṣe Ìwádìí iye àwọn tí o le ti ni àrùn COVID-19 tàbí tí ó ní ìdáhùn tó lágbára sí abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 nipasẹ̀ wíwọn ìpele agbógún-ti-àìsàn tó wà nínú ẹ̀jẹ̀ won.
- Eléyìí ṣe pàtàkì púpọ̀ pàápàá jùlọ bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ti ń gba abẹ́rẹ́ àjẹsára tó ń gbógun ti àrùn COVID-19 tí a bẹ̀rẹ̀ ṣíṣe àkíyèsí bí àjẹsára na ṣe n ṣiṣẹ́ sí ní àgbáyé.
- Láti oṣù kẹrin ọdún 2020 ni àjọ tó n kópa nínú ìwádìí lórílẹ̀ èdè yí (National Statistics) àti ilé ẹ̀kọ́ gíga Yunifásítì ti Oxford ti bẹ̀rẹ̀ ètò ìwádìí lórí àjakalẹ̀-àrun yi fún ìjọba UK.

Llywodraeth Cymru
Welsh Government

HSC Health and Social Care

Scottish Government
Riaghaltas na h-Alba
gov.scot

**Àkópọ̀ ìwádìí** | **Ìwádìí lóòrí àjàkálẹ̀-àrùn COVID-19** | **Ti ẹ̀yà 9.0 Ọjọ́:** Ọjọ́ kejìlélógún, oṣù keje ọdún 2021 | **Ètò ìtọ́kasí:** 20/SC/0195
**Ìdámọ̀ ìdáwọ́lé IRAS:** 283248 | **Olórí Olùsèwádì:** Ọ̀jọ̀gbọ́n Ann Sarah Walker

# Kini idi tó fi yẹ kí n kopa?

- Láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ìgbógun ti àrùn COVID-19 ti nlọ lọ́wọ́, a ni lo ìdílé bíi tìrẹ láti darapọ̀ mọ́ ogunlọ́go àwọn ènìyàn tí ó ti n kópa nínú ètò ìwádìí lórí àjàkálẹ̀-àrùn COVID-19.
- Ìlọ́wọ́sí rẹ nínú ìwádìí yi, yi o ṣe ìrànlọ́wọ́ fún wa láti ní àwòrán àjàkálẹ̀-àrùn COVID-19 ní agbègbè rẹ. Eléyìí a ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn elétò ìlera ní agbègbè rẹ ni ọna totọ ati ti o peye.
- Kìíṣe pe a nṣe àyẹwò fún àwọn tí ó ní àmì àrùn yìí lára, bíi ibà tàbí ikọ́ nìkan, nítorí a mọ dájú pé ni ìgbà míràn, àwọn ènìyàn leè ní àrùn yí láì fi àmì hàn.
- Kíkópa nínú ètò iwadi yìí, kìíse tipátipá. Gbogbo àlàyé tí o bá fún wa ni a o dáàbòbo lábẹ́ òfin, yí ò sì wà ní ìpamọ́.
- Gbogbo àwọn tí ó wa ninu ètò iwadi yìí leè gba abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 nígbàtí wọ́n bá yẹ láti gbàa – béèni àwọn èèyàn tí o ba ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 leè kópa nínú ìwádìí yìí.

# Kíni àwọn ohun tó rọ̀mọ́ ìwádìí yìí?

- Ọ̀kan nínú àwọn elétò ìwádìí yìí, yí ò wá sí ilé rẹ wọn yi o si beere àwọn ibeere nipa èèyàn kọọkan ti ọjọ ori rẹ bá tí le ni ọdún méjì tí ó fẹ́ kópa nínú ìwádìí yìí.
- Won yi o ṣe afihan fun àwọn ti ọjọ ori wọn wa ni ọdun mejila àti ju bẹẹlọ bi a ṣe n gba itọ́ ọnà ọfun ati omí imú fúnra-ara-won. A ó bẹ̀ ẹ́ òbí tàbí alábojútó ki o gbàá fún àwọn ọmọ tí ọjọ́ orí wọn jẹ́ odun meji si mokanla. Ohun èlò tí a fí n gbàá dàbí kàn-ìn-kàn-ìn fẹ́lẹ́fẹ́lẹ́ tí a lọ́ mọ́ igi, tí kìí sì nini lára.
- Kòsí ọkàn nínú àwọn elétò ìwádìí yìí tí yóò wọ inu ilé rẹ, wọn yì ó sì mú ohun ìdáàbòbò ara ẹni wọn yì ó sì fi aye lati jìnà sí ara ẹni.
- A ó sì tún fe láti gba ẹ̀jẹ̀ díẹ̀ láti ara ẹnikẹ́ni tí ọjọ́ orí rẹ̀ bá jẹ́ mẹ́rìndílógún àti àwon tó jù bẹ̀ lọ. Kò jẹ́ dandan láti gbà fún eléyi.
- Wa se eléyi fún ara re nípasẹ̀ gbígba ẹ̀jẹ̀ láti ìka, nípa lílo àwọn ohun àyẹ̀wò ti a máa pèsè.

AYẸWO

**Àkópọ̀ ìwádìí** | **Ìwádìí lóòrí àjàkálẹ̀-àrùn COVID-19** | **Ti ẹ̀yà 9.0 Ọjọ́:** Ọjọ́ kejìlélógún, oṣù keje ọdún 2021 | **Ẹ̀tò ìtọ́kasí:** 20/SC/0195
**Ìdámọ̀ ìdáwọ́lé IRAS:** 283248 | **Olórí Olùṣèwádí:** Ọ̀jọ̀gbọ́n Ann Sarah Walker

**O le f'àyè fún:**

**A** Ìbẹ̀wò kan nìkan

**B** Ìbẹ̀wò àkọ́kọ́ àti Ìbẹ̀wò ọlọ́sọ̀ọ̀sẹ̀ fún oṣù kan (Ìbẹ̀wò márùn lápapọ̀)

**C** Ìbẹ̀wò àkọ́kọ́, ìbẹ̀wò ọlọ́sọ̀ọ̀sẹ̀ fún oṣù kan, àti ìbẹ̀wò ọlọ́sọ̀ọ̀sẹ̀ titi di ipari ètò iwadi yìí (ó kéré ju àbẹ̀wò mẹ́fà lápapọ̀). Ní báyìí, ètò ìwádìí yi ńlọ lọ́wọ́ títí di oṣù kẹrin odún 2022. A o jẹ́ ki o mọ̀ tí àyípadà bá wà.

Láti wo fídíò tí ó ṣe àfihàn àti gba ẹ̀jẹ̀ láti ìka rẹ, wo **www.ndm.ox.ac.uk/covid-19/covid-19-infection-survey/video-guides**

Láti wo fídíò tí ó ṣe àfihàn àti gba ohun èlò yí, wo **www.ndm.ox.ac.uk/covid-19/covid-19-infection-survey/video-guides**

## Báwo ni mo ṣe lè kopa?

Láti le kópa, o ní láti **fi orúkọ sílẹ̀ pẹ̀lú wa laifi àkókò ṣòfò:**

1. Pe àwọn elétò ìforúkosílẹ̀ lóri **0800 085 6807** (England), **0800 917 9323** (Wales), **0800 917 5825** (Northern Ireland), **0800 917 5824** (Scotland). Tí o kò bá le lo ẹ̀rọ tẹlifóònù, bí àpẹẹrẹ bóyá o kò lè gbọ́ dáadáa tàbí o kò lè so, o lè tẹ àtẹ̀ránṣẹ́ sí, **iqvia.covid19survey@nhs.net**

2. Tí o báti forúko sílẹ̀ tán, **ọ̀kan lara àwọn tí o ṣe ìwádìí, yó pè ọ** ní ìrọ̀lẹ́ ọjọ́ tó bá kun ọ̀la kí a wá sọ́dọ̀ re.

   Tí àsìkò yí kò bá rọrùn fún e, o lè yi padà sí ìgbà míràn. A ó gbìyànjú láti kàn sí o láàrin ọ̀sẹ̀ kan tí o bá fí orúko sílẹ̀.

3. Ní ọjọ́ àbẹ̀wò rẹ, **ọ̀kan lára àwọn elétò ìwádìí yí wá sí ile rẹ** láti parí ètò àbẹ̀wò. Kòsí ọkàn nínú àwọn elétò ìwádìí yìí tí yóò wọ inu ilé rẹ.

## Kíni àfàání kíkópa mi?

- Ẹnikẹ́ni tí ó bá kópa nínú ìwádìí yi, yí o fi ẹ̀bùn tíkẹ́ẹ̀ti àádọ́ta pọ́ùn ṣe ìfàjẹ (£50 voucher) fún àbẹ̀wò àkọ́kó tí wọ́n bá parí.
- Tí wọ́n bá tún parí àbẹ̀wò míràn lẹ́yìn àkọ́kó, ẹni kọ̀ọ̀kan yóò gba ẹ̀bùn tíkẹ́ẹ̀ti owó pọ́ùn lọ́nà mẹ̀ẹ̀dọ́gbọ̀n (£25 voucher).

**Àkópọ̀ ìwádìí** | **Ìwádìí lóòrí àjàkálẹ̀-àrùn COVID-19** | **Ti ẹ̀yà 9.0 Ọjọ́:** Ọjọ́ kejìlélógún, oṣù keje ọdún 2021 | **Ètò ìtọ́kasí:** 20/SC/0195
**Ìdámọ̀ ìdáwọ̀lé IRAS:** 283248 | **Olórí Olùsèwádì:** Ọ̀jọ̀gbọ́n Ann Sarah Walker

AYEWO

Ẹ̀bùn tíkẹ́ẹ́ti wa fún àbẹ̀wò tí o ba parí nìkan. Tí wọ́n bá dá ìwádìí yìí dúró, tàbí o yàn láti yera nínú ìwádìí yìí, kò sí ẹ̀bún fún ìwádìí tí kò wáyé.

## Kíni ó ma ṣẹlẹ̀ sí àwọn àlàyé tí mo bá fi sílẹ̀?

- Gbogbo àlàyé tí o bá fi sílẹ̀ ni a o dáàbòbò lábẹ́ òfin, yí o sí wà ní ìpamọ́.
- Gbogbo àwọn àlàyé yi ni a gbà fún àjọ tí o darí ìwádìí ní orílẹ̀-èdè yí (National Statistics) àti ilé ẹ̀kọ́ gíga Yunifásítì ti Oxford.
- Gbogbo àyẹ̀wò lori àwọn àlàyé ni ile ẹkọ giga Yunifásítì ti Oxford àti ilé iṣẹ́ àyẹ̀wò National Lighthouse Laboratories yi o ṣe.
- Gbogbo èsì àyẹ̀wò pátápátá ni won yi o so fún ẹ.
- Àwọn ilé iṣẹ́ tí ó wà ní ìdí iṣẹ́ ìwádìí yìí, yi o lo àlàyé rẹ nìkan fún ètò ìwádìí yi – jọ̀wọ́ wo ìwé pélébé tí ó ní ọ̀rọ̀ lórí olùkopa fún àlàyé ní kíkún lori ohun tí ó ma ṣẹlẹ̀ sí àwọn àlàyé tí mo bá fi sílẹ̀.
- A ti fi èsì ìwádìí yìí síta kí àwọn ènìyàn lè mọ kíni ohun tí a n ṣe ìwádìí le lórí **(www.ndm.ox.ac.uk/covid-19/covid-19-infection-survey/results).** Kòsí ǹkankan nínú àlàyé yìí tí o ṣàfihàn iwọ tàbí ẹbi rẹ.

## Fún àlàyé síwájú àti website tó ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé:

Láti wo fídíò tí ó ṣe àfihàn àti gba ẹ̀jẹ̀ láti ìka rẹ, wo **www.ndm.ox.ac.uk/covid-19/covid-19-infection-survey/video-guides**

Láti wo fídíò tí ó ṣe àfihàn àti gba ohun èlò yí, wo **www.ndm.ox.ac.uk/covid-19/covid-19-infection-survey/video-guides**

Àwọn ẹdà ìwádìí yìí ní èdè míràn àti àlàyé míràn lórí ìwádìí yìí wa lori **www.ons.gov.uk/cis/languages**

Fún àlàyé lẹ́kùnrẹ́rẹ́, wo àlàyé lóri ìwé àkópa tí a so mọ́ ìwé yi, tàbí kí o wo ẹ̀ro ayélujára **www.ons.gov.uk/cis**

**Tí o ba ni ìpalára nípa eyíkèyí àwọn ǹkan tí a sàlàyé nínú ìwé pélébé yìí, tàbi o nwa àlàyé lórí àjàkálẹ̀-àrùn COVID-19 jọ̀wọ́ lọ sí:**

- Àlàyé àrùn coronavirus: **coronavirusexplained.ukri.org/en/**

**Àkópọ̀ ìwádìí** | **Ìwádìí lóòrí àjàkálẹ̀-àrùn COVID-19** | **Ti ẹ̀yà 9.0 Ọjọ́:** Ọjọ́ kejìlélógún, oṣù keje ọdún 2021 | **Ètò ìtọ́kasí:** 20/SC/0195
**Ìdámọ̀ ìdáwọ́lé IRAS:** 283248 | **Olórí Olùsèwádì:** Ọ̀jọ̀gbọ́n Ann Sarah Walker

- Àwọn ìtọ́sọ́nà ìjọba: **www.gov.uk/coronavirus** (England), **www.gov.wales/coronavirus** (Wales), **www.nidirect.gov.uk/campaigns/coronavirus-covid-19** (Northern Ireland), **www.gov.scot/collections/coronavirus-covid-19-guidance/** (Scotland)
- Ìmọ̀ràn àwọn àjọ elétò ìlera NHS: **www.nhs.uk/conditions/coronavirus-covid-19/** (England), **www.gov.wales/coronavirus** (Wales), **www.nidirect.gov.uk/articles/coronavirus-covid-19-overview-and-advice** (Northern Ireland), **www.nhsinform.scot/illnesses-and-conditions/infections-and-poisoning/coronavirus-covid-19** (Scotland)
- Samaritans – Àtìleyìn Imọ́lára fún gbogbo ènìyàn: **www.samaritans.org**
- Mind – Ìmọ̀ràn àti àtìlẹyìn fún ẹnikẹ́ni tí o bá ní wàhálà àìlera ọpolọ: **www.mind.org.uk**

AYẸWO

**Àkópọ̀ ìwádìí** | **Ìwádìí lóòrí àjàkálẹ̀-àrùn COVID-19** | **Ti ẹ̀yà 9.0 Ọjọ́:** Ọjọ́ kejìlélógún, oṣù keje ọdún 2021 | **Ètò ìtọ́kasí:** 20/SC/0195
**Ìdámọ̀ ìdáwọ́lé IRAS:** 283248 | **Olórí Olùṣèwádi:** Ọ̀jọ̀gbọ́n Ann Sarah Walker